JOVIAL NAPS

22xxbk

For 3 Sure draws in week 36 come to M. O. Oketọna 15 Oke Ọla St Apomu-Ikire before 3. p. m. Saturday

1, 9. 10. 22, 29.

# Imọlẹ Owurọ

Esin oro wa "IMOLE DE ỌKUNKUN PARADA"

UNITY NAPS

For 3 sure draws in Wk 36 try to see The Manager Unity Pools House E4/226, Gbelekale Ibadan

See him with N5 before 2 p. m. on Saturday

2 5 8 22 26

THE EDITOR IMOLE OWURO 6/4/74

IBADAN UNIVERSITY LIBRARY 9 APR 1974

Independent Paper VOL. XI No 634 SATURDAY ARRIL 6— FRIDAY APRIL 12, 1974 4K. (KỌBỌ MẸRIN)

# MEHAAYA ṢA IYAWO BAALE PA S'ỌNA OKO

ỌKUNRIN kan ti o haaya ile lati maa gbe ni ilu Ilie lẹba Ikirun ti fi ada ṣa iyawo Baale ile na pa si ọna oko.

Ọkunrin mehaaya na ni Tiamiyu Adigun ti o nṣiṣẹ agbafọ; ẹniti o ṣapa ni obinrin abilekọ kan Ọmọyeni Ayọka ti iṣe iyawo Baale rẹ Ọgbẹni Mọnmọdu Ikẹọla.

Ni ọjọ kokandinlogun oṣu kẹta ọdun 1972 ni ọdaran na ṣiṣẹ buburu yi gẹgẹbi awọn afẹṣunkanni ti wi nile ẹjọ.

Ọkọ obinrin na Ọgbẹni Mọnmọdu Ikẹọla sọ fun ile ẹjọ pe ninu ile oun ni oun joko si ni ọjọ iṣẹlẹ na ti oun ri i ti ọkunrin ọdaran na yọ si oun lojiji ti o si nsọ fun oun pe, oun (Tiamiyu Adigun) ti pa iyawo oun si ọna oko ki oun lọọ wo o.

Ọkunrin na sọ pe bi ọdaran na ti wi bayi ni oun ṣakiyesi pe ẹjẹ mbẹ lara rẹ, oun si di i mu, oun si fa a lọ sile Ọba Ilie nibiti Ọba na Ọba Adebayọ Akanji ti ranṣẹ pe Eesa re Oloye Salami Oyebọde.

Siwaju si i, ọkọ obinrin na sọ pe ọkunrin ọdaran na tun jẹwọ gba—ngba pe nitootọ ni oun pa obinrin na sọna oko.

Ninu idahun si ibeere Amofin M. A. Fatoki ti iṣe agbẹjọro ọdaran na, ọkọ obinrin yi sọ

(Wọju ewe kẹjọ)



NJẸ o ranti pe o to ọsẹ melo kan ti a ti ngbe iru aworan yi jade? Eniti o wa ninu aworan yi ni LUTZ PHILIPP nibi are ije kan.



W o Aworan ẹgbe osi yi wo. Kini o ise ???? x x 1—2 x??

## AKIYESI PATAKI FUN ONKAWE

LATI ọjọ Satide ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu karun ọdun yi (4/5/74), ai owo iwe irohin IMỌLẸ OWURỌ yio di kọbọ marun (5K)

Ohun ti o fa afikun owo iwe na ni wiwọn ti iwe itẹwe ati ohun gbogbo miran ti a fi ntẹwe wọngogo bi imi ẹegun lati ri ra. E o ranti pe o pẹ diẹ ti awọn iwe irohin yoku ti sọ iwe tiwọn di kọbọ marun

Nitorina, a ni ireti pe awọn onkawe yio ti mọ pe ọran yi ki iṣe ọran ẹnikan kọ ri-aiye ni. adura ni a si ngba ki o ma ṣe ju bayi lọ ki ọpọ iwe irohin ma ba kogbasile.

A ni ireti pẹlu pe ẹnyin onkawe yio fọwọsowọpọ pẹlu wa, a si nṣe ileri pe e o maa gbadun wa pẹlu ninu eto titun miran lailpẹjọjọ.

—OLOOTU

# ATIORO OMO AJIALA

## EWE IWOYI [6]

Oni l'o d'ose mefa
Ti a ti nsasoye
L'ori oro ewe iwoyi;
Ti a ti nketantan
L'ori awon ewe wa;
Pe, iwa aito
L'opo ewe wa nhu
Nipa pe:
Nwon nlo agidi,
Nwon mbu alase,
Nwon nhuwa aigboran.
Nwon nte ofin loju,
Nwon mbu arugbo
Nwon mbu enikeni,
Nwon np'agba ni were.
Nwon np'arugbo lalai-
gbon.
Nwon ni
Awon nikan
L'o le sohun gbogbo,
Nwon ni
Eni bi eni
L'omode i kawo.
Eji bi eji
Eni ba ji ni
Laa a ji
Eta bi eta,
Eni ba ta ni,




L'a a ta;
Erin bi erin
Eni t'o rin ni
L'a a rin;
Arun bi arun
Eni t'o run ni
L'aa run;
Efa bi efa
Eni t'o fa ni
L'a a fa;
Eje bi eje
Olugbon joro
O kije,
Nje k'a too kije oro yi
L'ese t'o mbo,
O ye ka tun so
Iru itu gbogbo
T'awon ewe npa;
O ye ka soro asiri
Ti gbogbo ewe mbo,
Nitori ope iwa
Ni nwon nhu
Ti ko ye k'a dake si
T'o je pe
Bi a ba dake,
O le d'ojo iwaju
Ko tun fon wa n'ikun
Enyin obi pata,
E ngbe tabi e sun?
Nje e mo pe
Ope odo l'o wa
Ti nse buburu!
Nje e mo pe
Iwa t'odo miran nhu
Buru yeye ju
Ohun agba nhu le!
Nje e mo pe
Odaran t'o wa
Ninu ewe iwoyi poju
Odaran agbalagba le?
Nje e mo pe
Majesin miran bura
T'o fere tayo t'esu eda-
ra
Tabi e ko ranti
Iye omo ile iwe
Ti nwon ti mu
Fun esun ifipajale?
Tabi e ko ranti
Iye omode akeko
T'o ti nje jo fadiya?
Tabi e ko ranti
Ope odo
Ti nmu igbo?
Tabi e ko ranti
Iye omo sukuru
Ti a ni ale
Bi ogun, bi igba?
Iwo obi omo sukuru,
Nje o ranti
Igba t'omo re gba
Owo sukuru tan
T'o ko gbogbo re f'obin-
rin?
Nje o mo
Iye igba t'omo re obin-
rin
Gba owo lowo re tan
T'o fi ra ewu f'okunrin?
O ranti owo afipawa
T'omo re paro gba tan
T'o amu un relo asewo?
O ranti owo tipatipa
T'omo re mu re hoteeli?
O ranti eyi to paro gba
T'o nmu rode olege,
T'o tun amu lo
Sile ijo gbogbo
Ati sile ikose iwa esu
Ti nwon npe ni
Sinnima?
Tabi o ti gbagbe
Omo re obinrin
T'o l'oun nlo Sukuru
T'o je pe ile okunrin
Lalakiri nlo gbe!
Tabi eyi t'o pamopo
Pelu elegbe re
Ti nwon npaio owo!
Tabi eyiti o yiwe lisunwo

T'o nyi ceji secta!
Iwo ngbaaru ka,
Omo re njalye!
O nriru eyi
O ni ko si nkan!
Se o ti reyi
Ti nwon ran re koleeji
T'o gboyun wale!
Se o r'eyi
T'o fee seyun
T'o gbona orun lo!
Se o r'eyi ewe
Ti nkawe lowo
T'o lo se "Feto si i"
Nitori ko le ribi
Maa sise asewo kiri?
Iwo obi,
Oro yi kan o
Tabi ko kan e?
O r'iru re ri
Ta boo ri i ri?
Se o ye ka fowoleran
K'a maa woran ni?
Se ko ni i yowo yese
F' orile ede?

OLOLA ATIORO



On'ruuru ise ona ati ise owo ni o wa ni oniruuru Orile ati ede ni agba nla aiye, Ani, gege bi awa na ti ni iru nkan ba-wonyi ni a le ri i ni ile miran, ti o si je pe awon miran ju ara won.

Aworan egbe yi nse afihan ise ona ere gbigbe ti gbajumo agbegilere omo ile Russia kan Yergeny Vuchetich gbe. O pe oruko ere na ni "Ibanuje Iya lori omo Agbegilere na kundun ki o mai gbe ere ti o jemo itan Orile—ede"

# Oku Abebo koyoyo

Isawo oku Oloogbe Iyaafin Hannah Abebo Adeniji ti ise iya Ogbeni John Adeniji. Eni odun marundinlaadorin ni oloogbe na ise.

Ojo Eti ti ise 15/3/74 ni sisi, ojo Satide ti ise 23/3/74 si ni eto inawo sele lehin isin ikehin ti nwon se fun un ni ile Olorun Ijo Onitebomi Loru, Ogbomoso; Alfa Oloye S.A. Ige lo se adari eto isin na.

Ninu awon ero re na, Eni Owo Igefiki awon omojooku ati ebi oku na ku asehinde oloogbe na.

Lehin na ni Eni-Owo Ige so nipa akitiyan Iya na ninu ijo Olorun ati laarin awon elegbe re pelu, o si se akawe re gegebi 'Onigbagbo otito lati aiye de ajule orun,

Lehin isin inu ile Olorun ni awon ioo se isin fun un ni eti boji ite oku ki fanji too bere. Orisirisi elegbejegbe, awon ebi ati ara gegebi egbe, bi ore, bi gbajumo l'o pese sibi inawo oku na.



OLOGBE ABEBO ADENIJI

AKEDE ỌNA IYE

# Mase Gbero buburu mo


WOLI S. I. OWOẸYẸ
Onlwasu ee

"NITORI lati inu ọkan ni iro buburu ti ijade wa: Ipania, panṣaga agbere' ọlẹ, ẹri eke, ati ọrọ buburu, ohun wọnyi ni i sọ enia di alaimọ": Mathew 15, 19—20.

Jesu Kristi Oluwa ni o nfi ọrọ nla yi powe l'oju awọn ọmọ ẹhin rẹ Nipa bẹẹ, Jesu Kristi nfi ye wa pe, ohun—kohun ti a jẹ sinu ko le sọ enia d alaimọ bikoṣe ohun ti o ti inu jade

ọkunrin ọmuti yi ba tilẹ ni ero buburu kan ninu ọkan rẹ lati sọ jade, ọti yi ni yio ran an lọwọ. Nipa bẹẹ' a di enití nro ero buburu jade li ọkan rẹ bi: agbere, ole jija, ija jija ati ẹbẹbẹ lọ pẹlu ọrọ buburu jijade lẹnu. Iru ọrọ buburu ti o ba njade l'ẹnu ọmuti na

oogun ika kiri. A ni, bi oni ko ba ni oogun ijakadi lọwọ, ti nwọn si yaju si oun ni ode l'ọjọ iwaju, kini oun yio fi ṣe ọkunrin, ni yio ba lọọ ṣ'oogun ijakadi sowọ.

Elomiran a ti ipa iru ero bubur bayi maa ṣ'oagun ejọ kiri, a ni nitoripe oun le lọ sibikan ki ejo bu oun jẹ. Omiran a tilẹ maa ṣe oojruuru oogun ika sọwọ, ani nitori bi oun ba lọ s'ode ki oun le ri nkan fi ba alafọjudi enia ja.

Ero buburu lati inu ọkan bayi ni o nsọ enia di enia buburu ati enṣẹ buburu tobẹẹ ti o jẹ pe ẹniti yio huwa buburu si ni yio maa wa kiri: iṣẹ ibi a si kun ọwọ iru ẹni bẹẹ nigbagbogbo nitoripe bi ọkan rẹ ti ri ni iṣẹ ọwọ rẹ ri.

Idi niyi ti awọn Yoruba fi npowe pe "Iwa ọmọ eli mu ọmọ jẹ ekigbe." Ṣugbọn ṣa o, ibi ni elero buburu enia paapaa yio maa ba pade ni ọna rẹ gbogbo.

Nitorina, mo nkesi olukuluku enia l'oni, l'ọkunrin ati l'obinrin lati sa fun erokero; nitori bi erokero ba wa ninu enia; bo ba ṣe enia l'oni, yio ṣe araa rẹ lola. E gbọ itan kekere kan nipa elero buburu.

ITAN

Ni akoko kan, Baba onisowo kan gbera ni ilu Ibadan lọ si Eko lati ra ọja. Ṣugbọn owo ti Baba yi mu lọwọ poju ọja ti o fee ra lọ. Ṣugbọn nigbati Baba na de budo ọkọ Ogunpa lati wọkọ, o ba alabagbele rẹ kan t'o haaya ile lọwọ rẹ pade, o si fun ni igba Naira (N200) pe ki o ba oun fii pamọ di ọjọ keji ti oun yio ti Eko de nitori o mbẹru bi jaguda le da a l'ọna; ati pe nigbati oun ti ri enia ti oun le fii le lọwọ, ko mu ọgbọn jọwọ mọ ki oun tun di mọra lọ s'Eko.

Ṣugbọn s.bẹ, Baba yi ko huwa emugẹ, o ṣe iwe kekere kan le alabagbelẹ rẹ na lọwọ, eyiti o fi han pe oun fuu un ni igba Naira fun ipamọ di abọ ajo oun ni ọjọ keji. Bayi

ni Baba na wọkọ ti o si ba ọna ajo rẹ lọ.

Ṣugbọn ki alabagbele paapaa too fi idiko silẹ, oun na ko nomba ọkọ ti Baba onile rẹ wọ silẹ. Ṣugbọn o ṣe ni laanu pe ogun ibuso pere ni o ku ki ọkọ Baba na de Eko nigbati ijamba ṣe ọkọ na ti gbogbo ero inu rẹ si ku! Radio l'o tilẹ kọ kede irohin iṣẹlẹ na fun gbogbo aiye

Nigbati alabagbele Baba yi gbọ irohin na l'ori redio pe ọkọ ti Baba na wọ l'o kagbako ati pe gbogbo ero inu rẹ l'o ku, ọ ni "Yes, mo ti bọsinu aiye wayi, Land lord mi ti ku sinu ọkọ yẹn; Ki ng maa na owo t'o fi si mi lọwọ l'o ku, Ng o na gbogbo rẹ pata Oku ko kuku le beere owo lọwọ alaaye mọ"

Ey n ọmọ enia, eyi ti ọkunrin yi ki ba fi kerora, ki o si daro, ile oti kan ni o lọmọ sapamọ si pẹlu ẹjẹwo kan t'o gbe owo na mọ em lọwọ.

Ṣugbọn ọjọ keji ni Baba olowo ti Eko de pẹlu ẹru rẹ kan! wahala nla de ba ọkan alabagbele yi nitoripe

(Wo oju ewe keje)

LATI OWỌ WOLI S I OWOẸYẸ

Fun apẹrẹ, bi enikan ba jẹ ọmuti ti o si bere sii mu ọti na pẹlu ọjukokoro, o le ma ṣe isọkusọ nigbati o ba nmuti na lọwọ; ṣugbọn lehin ti o ba ti mu ọti na tan ti ọti yi si sinmi sinu araa rẹ, yio wan bẹrẹ isọkusọ jade l'ẹnu: Ọti yi ti di ẹṣẹ sii ninu ẹnu rẹ si nsọrọ ẹṣẹ jade.

Eyi fi i han pe bi ni ọmọ araiye yio maa sọ kiri nipa re. ọrọ na ni yio si sọ ọ di alaimọ.

Apejnwe ni ọrọ ti a nsọ wọnyi je, Ibiti iwaasu wa l'oni nlọ ni lati kilọ fun enyin ọmọ enia ninu aiye yi lati sọra pẹlu ero buburu ti iṣe ero eṣe lati inu ọkan nyin wa.

Awọn ero buburu wọnyi l'o maa nfa a ti ẹlomiran fi maa nṣe

## Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

10,643 Owojabi Sofunmade Ibadan

10,644 Adebayọ Afọlabi, Ibadan

10,645 Isaac Kọlawọle Ile—Ife

10,646 Janet Andu, Ibadan

10,647 Ọlaleye Ṣodola, Remọ

10,648 Olujide Ọlaniyan, Ibadan

10.649 Ọladiti Ajadi, Eko

10,650 Iyiọla Asafa, Iwo

10,651 James Adie, Ẹdẹ

10,652 Jacob Isọla, Ṣagamu

10,653 Amusa Ijaodọla, Ọyọ

10,654 Jamiyu Ọriọla Ifo

10,655 Adigun Olumoko, Ekọ

10,656 Adewale Ajala, Ibadan

10,657 Anthony Oni, Ifẹ

10,658 Bilawu Aṣafa, Iwo

10,659 Raufu Idẹra, Mọniya

10.660 Alice Ori—ọla Ikirun


FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA DI

Omo Egbe Imole Owuro
(Iwe Idi omo Egbẹ)

Oruko rẹ ______________

Adirẹsi rẹ: ______________

Ọmo ilu ti o jẹ: ______________

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akowe Egbẹ)
P. M. B. 5230, Ibadan


## ANFANI FUN O

Kinni iṣoro rẹ ? Kinni ẹdun ọkan re ? Kinni o nru ọ loju? iwọ ha nlalakala bi ? Tabi ohunkohun nru ọ loju ninu Bibeli bi?

Ọfẹ ni a o fi gbogbo nkan wọnyi ye ọ. Fi apo iwe ti o lẹ Stamp 5k mọ ara rẹ, pẹlu addrerss rẹ sinu iwe ti o ba kọ si mi. Ero mi ni lati fi ẹbun ti a fun mi ran araiye lọwọ:

Kowe si:
Woli S. I. Owoẹyẹ
N6/763A Kabiawu Street
Mọkọla Ibadan.

ASỌTẸLẸ

"Ibi ni yio pa enia buburu ati awọn ti o korira olododo yio jẹbi; Orin Dafidi 34, 21

# Owo ni Orisun Ẹṣẹ (2)

GEGE bi a ti sọ ninu waasi wa ọsẹ ti o koja owo ni orisun ẹṣẹ t'o gajulọ. Gbọ itan yi ki ọrọ na le ye ọ yeke-yeke.

ITAN

Ni igba atijọ, eni Ọlọrun kan wa ti o maa nṣe waasi ododo, ati ẹniti o ni ifẹ si ati maa ba iṣẹ eṣu jẹ.

Ọkunrin yi ri igi nla kan ti awọn ọsẹbọ maa mbọ. Nigbati ilẹ ọjọ keji mọ, ọkuurin yi mu aake rẹ, o kọri si idi igi na lati ge e. bẹẹ ni Satanu ba yipada di baba agba kan, o ni ee-tiri ti ọkunrin yi fi mu aake wa si idi igi na? Ọkunrin yi dahun o ni oun yio ge igi na ni nitoripe awọn enia mbọ maa ge e ni baba agba ijọsi ti iṣe Satanu tun yọ si i pe, eetiri Alufaa si tun da a lohun pe, oun fẹẹ gegi na lulẹ ni nitoripe awọn enia nrubọ nibẹ ni nwọn ba tun wọ ijakadi.

Ṣugbọn ni ẹkeji yi, Baba agba yi (Satanu) ni o gbe Alufaa ti o si la a mọlẹ, ni Alufaa na ba bẹrẹ si i bẹẹ ki o fi oun silẹ. Satanu si fi Alufaa na silẹ.

Ṣugbọn Alufaa wa

LATI ỌWỌ ALUFAA MUDASIRU ALIYU

ọ. Satanu sọ pe ko gbọdọ ge e, ni awọn mejeji ba wọ ijakadi.

Lẹsẹkẹsẹ ni Alufa yi gbe Satanu bẹrẹ sii maa bẹ Alufa, o si ṣe ileri fun un pe ni gbogbo orooowurọ, Alufa na yio maa ba aadọta kọbọ ni igberi rẹ. Nigbati o di owurọ ọjọ keji nitootọ, Alufaa ba aadọta kọbọ ni igberi araa rẹ, o si mu un.

Bi o ti tun di ọjọ kẹta o ba a bẹẹ, o tun mu un. Ṣugbọn nigbati o di ọjọ kẹrin ni ko ba owo yi ni igberi rẹ mọ ni Alufaa ba tun pọn aake rẹ lati lọọ ge igi na bii ti akọkọ.

Bi o ti debẹ ti o fẹẹ beere lọwọ Satanu idi ti oun Alufaa fi da a ni ijọsi, ṣugbọn ti oun ko si le da a mọ bayi, Satanu si da a lohun pe, ni ijọsi, ẹmi ẹsin Ọlọrun ni o fi ṣe e, ṣugbọn ni ti oni yi, ẹmi owo ni o fi ṣe e.

Nitorina, enyin ti ngbọ waasi yi, ẹ jọ ki a fi itan yi kọgbọn Maṣe gba ọna ọdọ eṣu wowo, ma si ṣe na owo rẹ gba ọna ọdọ eṣu

Bi Ọlọrun ba ti kọ owo mọ ọ, ko si ohun ti o le pe ki o ma ni E jẹ ki olukuluku gba ọna ẹtọ wa owo nitori pe owo ni orisun ẹṣẹ.

## ANFANI FUN Ọ

Kinni iṣoro rẹ ? Kinni ẹdun ọkan rẹ ? Kinni o nru ọ loju? iwọ ha nlaiakala ẹ́ ? Tabi ohunkohun nru ọ loju ninu Bibeli bi?

Ọfẹ ni a o fi gbogbo nkan wọnyi ye ọ. Fi apo iwe ti o lẹ Stamp 5k mọ ara rẹ. pẹlu addrerss rẹ sinu iwe ti o ba kọ si mi. Ero mi ni lati fi ẹbun ti a fun mi ran araiye lọwọ:

Kowe si:
Woli S. I. Owoṣẹyẹ
N6/763A Kabiawu Street
Mọkọla Ibadan.

ASOTẸLẸ

"Ibi ni yio pa enia buburu ati awọn ti o korira olododo yio jẹbi; Orin Dafidi 34, 21

# Idanwo Kurani

1. Nibo ni aya ti o gun julọ wa ninu Kurani ?

2 Nibo ni aya ti o kuru julọ wa ninu Kurani

3 Nibo ni Kurani ti sọ iye akan ti eṣu fi tan Anabi Adamu ati Awawu jẹ, kin si ni awọn nkan na ?

4. Nibo ni a ti le ri i ninu Kurani, iyawo ẹniti o tọrọ ọmọkunrin ti Ọlọrun fun un ni Ọmọbinrin? Kini oruko ẹmọ na?

5. Obinrin wo ni Kurani sọ pe o kiye-si abe rẹ nipa pe ki ṣe agbere?

E tete maa fi idahun nyin sọwọ si.
Olukọ Mudasiru Aliyu,
c/o Islandeen,
Box 5,
Iwo



Aworan oke yi nṣe afihan Yvonne Mitchell ati Rex Harrison ninu ara kan ti nwọn pe ni "Henry IV". Aworan alare mejeji yi jẹ olokiki afare—da—ni—laraya ni ilẹ Gẹẹsi; ere wọn na ti nwọn pe ni "Henry IV" ni nwọn fi sọri Ọba ilẹ Germany kan ti nwọn npe ni Emperor Henry IV, ẹniti o jọba ni ilẹ na niwọn ẹgbẹrin ọdun sẹhin

*The imperialist powers consider the support rendered to the Smith racialist regime in Rhodesia as a weapon for "intimidating" the independent peoples of Africa.*
*(From the press).*




A KKK OFF-SPRING.

2
8
12
14



Aworan oke yi nṣe afihan iru ona kan ti awon agbe ngba sise oko won ni ona lọọrun nighakugba ti ogbe'e ba walẹ. Iru ona na ni a npe ni "IBOMIRIN". Aworan na nṣe afihan iru ipa omi bẹẹ ti o wa ni Hongry Steppe bi okunrin agbẹ kan ti nlọ o jati fi bu omi rin oko ogbin rẹ'

# ADAJỌ KILO FUN AWỌN ADELEBO OBINRIN

ADAJỌ ile ẹjọ ibilẹ Osogbo keji fun ẹka Ila Oorun Ariwa agbegbe Ọṣun Ọgbẹni Oni Ọbasa, ti kilo gidigidi fun awọn Adelebọ Iwọ-Oorun lọpọlọpọ lati ṣẹra nibi yiyan ọkọ iyanku-yan kiri, de ibi pe nwọn yio maa bimọ fun ọkunrin miran lai jẹ pe ile ẹjọ ti tu igbeyawo laarin awọn ati ọkọ wọn awarọ ka.

Ni ọjọ kejilelogun oṣu kẹta ọdun yi ni Adajọ Ọbasa ṣe ikilọ na ni ilu Osogbo nigbati o ndajọ ẹsun "biba aya mi ṣagbere" ti o nirohin kan ni ilu Ikirun Ọgbẹni Lasisi Ogunṣọla pe oṣiṣẹ ile iṣẹ eto ogbin kan ni agbegbe na Ọgbẹni Raimi Ajao.



LASISI OGUNṢỌLA
Okọlobinrin

Ọgbẹni Ogunṣọla ni o pe ẹjọ oji ọnirinwo Naira (N400) sile ẹjọ n pe ile ẹjọ gba owo na fun oun lọwọ Ọgbẹni Ajao nitoripe o ba iyawo oun Arabinrin Adikatu Ejide ṣagbere tobẹẹ ti obinrin na fi bimọ mẹrin fun un lai ba ofin mu.

Ninu ọrọ re nigbati nwọn nṣejọ ni lọwọ Ọgbẹni Ọdẹtoyinbo ti iṣẹ Agbẹjọro Ọgbẹni Ogunṣọla rọ ile ẹjọ na lati pasẹ pe ki Ọgbẹni Raimi Ajao san irinwo Naira fun ẹlẹjọ oun lai din kobo ki o le jẹ arikọgbọn fun ọkunrin miran ti o ba fẹẹ da iru rẹ l'aṣa.

Ọgbẹni Ogundere ti iṣẹ Agbẹjọro Ọgbẹni Raimi Ajao rọ ile ẹjọ na lati ṣiju aanu wo ẹlẹjọ oun.

Ninu idajọ re, Adajọ Alagba oni Ọbasa sọ pe iru iwa iṣagbere bayi wọpọ ni ibi, awọn ẹlẹjọ na ti wa

(Woju ewe kefa)


## KERE O! KERE O!!

***Bi o ba je onisowo ti o nfe ki oja re maa ta; ti o si nfe ki oja re gbajumo kari aiye gegebi iwe irohin IMOLE OWURO ti gbajumo; darapo pelu awon enia atata ti o npolowo oja won sinu Imole Owuro.***

***Fun alaye ekunrere nipa bi o se nilati se e ati iye ti o nilati san; wa sile ise wa tabi ki o kowe si:***

**Advertisement Manager**
**(Imole Owuro)**
**N4/496B Yemetu Aladorin**
**P. M. B. 5230**
**Ibadan.**



IWE IGBAELODE DARA PUPỌ

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 10k
2. Kurani esu marun Yoruba 55k Esu kan (25k)
3. Yasin ni Yoruba (10k)
4. Zabura ati itumọ (55k)
5. Zabura Yoruba (40k)
6. Iwe Aiye Akamara (40k)
   Iwe owe enia ṣoro 40k
7. Adedẹwọ (35k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (N3); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni nla (N1. 50)
10. Kekere(30k)
11. Iwe oogun Iwosan (N1. 5) Kekere (45k)
12. Itan Anabi ati Yisa (55k)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (25k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaelode N2/394a, Odoye Adeoyo Rd, P. O. Box 3365, Mapo Ibadan.

(2) Alufa Igbaelode, Mọṣalaṣi Idi Iṣin St Isalẹ Koto P. O. Box 17 Ilọrin



# Baba pa Qmo re L'apagbe



Aworan oke yi nṣe afihan awọn oṣiṣẹ ti o maa afin awọn ẹranko kan ti nwọn npe ni "Agba-nrerej' Nwọn ti kẹko jade nile ẹkọṣẹ ogbẹni ti nje Magadaa ni Ọla ti nṣe ilu kan lati okun Okhtak ni ilẹ Russia.

Bi ẹ ba kiyesi aworan daadaa, ẹ o ri i pe ori ẹranko na ni o wa l'ori tabili nnl.

ILE ẹjọ g'ga ilu Ado Ekiti labẹ aga Adajọ Ọlọla Sikiru Ayinla si da okunrin kan George ọnọ silẹ l'ori esun pe o pa ọmọbinrin rẹ kan Olubunmi George ni Igede Ekiti ni ọjọ kerin oṣu kẹfa ẹdun 1972.

Awọn afẹsunkanni sọ pe ọkunrin na ti o ngbe ni ojule kẹsan opopo Irolo ni Oke lọrọ Igede Ekiti, pa ọmọbinrin na ti iṣe ọmọ bibi inu rẹ, eyiti o lodi si ofin orilẹ ẹde Naijiria.

Sugbọn nigbati Adajọ ndajọ na ninu ọsẹ yi, Adajọ Ọlọla Sikiru Ayinla Abina sọ pe gẹgẹ bi ẹri ti o wa niwaju ilẹ ẹjọ, opolo okunrin na ko pe ni akoko ti o pa omo re na.

Nitori ọran yi Adajo na sọ pe oun ko le da ọkunrin na lẹbi ipania nitoripe ori re ko pe, o si dajo pe, okunrin na ko jẹbi.

Ṣugbọn Adajọ na paṣe pe ki nwọn lọọ fi okunrin na pamo si ogba ẹwon titi Gomina Ologun Ipinle Iwo—Oorun yio fi wo'kan ṣe l'ori rẹ. Adajo so pe lowo Gomina na ni emi re wa bayi.

Ṣugbọn ninu ile ejo yi kanna, Adajo ile ejo na da okunrin kan David Obue lebi Iku, fun jijebi esun ipani ti nwon fi kan an.

Awon afesunkanni ni o fi esun kan odaran na pe o pa Ijoye kan Oloye Emmanuel Ogunmola, eni aadọrin odun ni Ugbo Akoko lẹbi Ikarẹ ni agbegbe Akoko ni ojo

(Wo oju ewe keje)

## Adajo kilo

Lati oju ewe karun o si kesi awon eniyan lati dekun bibu iru iwa bee.

O ni eri ti o wa niwaju ile ejọ fihan pe Ọgbeni Raimi Ajao ba obinrin na sagbere. O ni bi o tile je pe obinrin na ti jawe ikọsile fun ọkọ re ni ile ejo ibile Onipokeji adugbo Oke-Are nilu Ibadan, ati ni Ikirun, ko si eri pe awon ti tu igbeyawo ka laarin oun ati oko re ewure.

Adajo na so pe, nitori idi eyi, Ọgbeni Lasisi Ogunsola ni oko obinrin na sibe labe ofin, o si paṣe pe ki Ọgbeni Raimi Ajao loo san Naira mej,lelogorin ati ogota kobo (N102.60) fun Ọgbeni Lasisi Ogunsola l'ori oro na.



Aworan ti apa osi ni ẹgbẹ yi nṣe afihan Ọgbẹni Boris Volynor pelu ọmọbinrin re Tanya bi nwọn ti nfi igi ọdun Keresimesi ṣere, Ọgbeni Boris yi je ọkan ninu awọn onigboiya ọmọ ile Russia ti nwọn imaa yọọda araa wọn lati lo fun iwadi Baalu ele—nmọ ti nwọn fmaa ran si oke ọrun.

*Aworan ti egbe ni ọtun ni ti awọn omọ ile eko giga kan ni ilu Ashkhabad ti iṣe olu ilu Turkmasin bi nwon ti nṣe akojo oniruuru ebun ti nwon yio fi sowo si awon odomode ni ile Vietnam nibiti awon ti ajagun lowo lai siwo ni igbakan;



# IDILE MIRAN KOWE LORI OYE OBA OSOGBO

IDILE miran lati ilu Osogbo—Idile Adedunhan t agbo ile Laylokun, ti kowe ebe kan si ibi ise akoso oran Lobalobe Ipinle Iwo—Oosun, ninu eyi ti awon na fi ilodisi won han si iwe ilana jije Oba Osogbo, eyiti o ti waiye lati odun 1958.

E o ranti pe lati igba die wa ni oni—ruuru idile ti nwon so pe awon leto si jije Oba Osogbo ti bere sii fi iru iwe ilodisi bee sowo si Ibadan, ti nwon nso pe awon ko mo ti iru akosile odun 1958 na fi waiye, ati pe, aisedeede wa ninu ate na pelu; nwon si nkesi Ijoba lati se iwadi l'ori oro na; ki atunse le waiye.

Laipe yi ni idile Adeduhan ti a wi yi kowe tiwon na si ibi ise akoso oran Lobalobe ni Ibadan l'ori oro yi; Ogbeni Adesina Durosomo ti ise agbe—joro kan niiu Osogbo ni o si ba won kowe na.

ITAN

Ninu iwe won na, idile yi so pe Baba—nla

Lati owo Adisa Adeniyi, Osogbo

awon ti Ije Adeduhan ni Aremokunrin Lajomo eniti nwon so pe oun ni o ko je oye Ataoja Osogbo, ati pe, oku re ni awon ko sin si ile Osin ti Oja Oba Osogbo gege bi Oloye kini.

Nwon ni Adeduhan ni eto lati joye, sugbon fun idi miran, Laro ti ise aburo re ni o joye. Nwon ni sugbon lehin iku Laro, Laylokun ti ise omo bibi inu Adeduhan du oye Ataoja pelu aburo re ti nje Aina Serubu ti apele re nje Sogbo, sugbon oye na bosowo Serubu.

Nwon ni bakanna lehin iku Aina Serubu, omo Laylokun ti aje Iyalola du oye pelu Ojo Okege ti nwon so pe o ti idile obinrin jade, eniti o mu oye na je.

Siwaju si i, idile na so pe lehin iku Ojo Okege ni omo Laylokun kan ti nwon npe ni Oyeyemi tun du oye;

(Woju ewe kejo)

## Sadatu Asabi saisi

Ni ojo kejidinlogun osu keta odun yi ni Arabinrin Sadatu Asabi ku ni ile Babala, Oke-Igtu, Popo Giwa nilu Ilorin

Opo omo ati omo—omo l'o gbehin iya na. Ara won ni Alhaja Morinmo Ajibiye, Ay—satu Nana Baba Osogbo, Alhaji Saabu Aleo ofi.

Opo enia l'o wa sibi isinku na. Ara won ni Imamu Amuda Ilela, Imamu Agbagi, Imamu Ojibara ati beebee lo.

## Baba pa omo re

(Lati oju ewe kefa)

kini osu karun odun ti o koja

Enia mejo l'o jeri gbe Ijoba ninu ejo na; sugbon odaran na so pe, oun ko jebi esun na

Sugbon ninu idajo re Olola Abina so pe iro ni odaran na pa. O ni oun gba eri ti gbo—gbo eleri Ijoba je gbo, ati pe, eri ododo ni ise

Nitorina, Adajo so pe okunrin na jebi iku, o si pase pe nse ni ki nwon sokun mo en l'orun titi emi re yio fi bo.

## Owoeye

(Lati oju ewe keta)

o ti wo gbese nipa ero buburu t'o ti wo inu re pe olowo yi ko si ninu aiye mo!

A! iwo omo enia, o ri okan tabi o ko ri i? Mo nwi fun o l'on; Tete tun okan re se nitori lati inu okan ni ero buburu ti nwa.

ADURA

Oluwa, pa okan mi mo kuro ninu ibi, Amin.

# 28





... awon egbe odomode ile Russia bi won ti nki Ogbeni Yevgeni Khrunovi nse onigbeya omo ile na ti o nwa oko oramo-nda kaakiri ayika saanmaawa lehin aiye ti wayi ku abo irinajo na.

# IDILE MIRAN KOWE LORI OYE OBA OSOGBO

(Lati oju ewe keje) şugbon lehinti ilu ti yan an lati joye, ti awon si npale oye mo ni o ku, ti Fabode ti nwon so pe o wa lati idile obinrin si fi jeba.

Idile yi so siwaju pe ninu ọdun 1944, Idowu ti işe ọkan ninu ọmọ Layiokun ba Ọba Adenle ti o wa lori itẹ l'oni du oye ti ko si ri i je.

Nwọn pitan siwaju si i pe idile Morondiya Ojigan ti işe ọmọ Sogbo keji ti nwon si tun je ibatan Layiokun ti şorire lati joye Atọọja. Nwọn ni ara wọn ni Kọlawole ti o joye ni ọdun 1920 titi di ọdun 1933; ati pe, "ninu idile yi ni Ọba Samuel Adenle ti o wa l'ori itẹ l'oni ti wa lati jeba."

Idile na wa sọ bayi "Awọn Ataoja wọnyi: Sogbo, Aina Serubu, Kọlawọle ati Ọba Adenle t'o wa lori itẹ l'oni je aromọdọmọ Adedunhan ti işe Baba—nla wa."

Ninu iwadi nipa itan Ọba t'o ti jẹkọja ni ilu Ọşogbo, akọsilẹ ti o rẹ mi lọwọ sọ pe:

Ni ọdun 1760 ni a te Oşogbo do. Ninu odun 1819 ni Ọranjuwon joba; ni odun 1819 ni Laro joye, oun si ni Ataoja akoko, Ajibulu (1822) Sogbo (1825), Aina Serubu (1832) Beyioku (1833); Ọladele Lahanmi Oyipi (1840) Ojo Ọkege (1854), Matanmi (1864) Fabode (1878) Bamgbola (1891), Oyetola (1893), Gbeja (1903) Latona I (1918), Lawole (1920), Oyedokun Latona II (1933) Samuel Adenle I (ti o wa l'ori ite lati 1944.

Mo tun de ile işe Igbimo Ijoba Ibile ilu Oşogbo nwon si so fun mi nibe pe awon ri Iwe idile Adedunhan gba. Bakanna ni ile işe akoso Ọran Lobaloba ni Ibadan so fun mi pe awon ti ri i gba pelu şugbon Ọga kan pataki nibe ran mi leti pe, Ijoba ti kede şaaju pe atunşe yio wa fun gbogbo akosile jije Ọba ti aleebu ba wa ninu re jakejado ile Iwo—Oorun ati pe eto na ki yio pe bere.

Ninu oro tire, Ataoja Oşogbo Ọba Samuel Adenle so fun mi pe "Otito, awon molebi ti nje oye po pupo, ki i si işe ete lati le maa daruko enikookan ninu Iwe"

O fi kun un pe, o ye, o si to fun awon ti nwon ba ro pe ireje l'o je fun awon, lati gbe oro won sita fun atunşe.

Lati igbati nwon ti nje Oye Ataoja, ko si akosile kan ri bikoşe pe eyiti nwon şe ni odun 1958 yi na ni ekinni, Bi atunşe kan ba si ye, o ye ki nwon şe e.



Ann Jones ti o mọ ere booiu eleyin igba daradara ni ẹ nwo nni pelu Billie—Jean King.

## Alagbafo Egba gbawe Egbe

Ni ọgbọnjọ oşu kẹta ọdun yi ni Alake ile Egba Ọba Lipede gbe iwe eri ẹgbẹ fun ẹgbẹ Alagbafọ ẹka Abẹokuta fun Olori ẹgbẹ na Ọgbẹni S. Bakare.

Ninu ọrọ rẹ nibi ayẹyẹ na, Ọba Lipẹde sọ pe inu oun dun pupọ si iwe eri ti ẹgbẹ Alagbafọ ile oun ri gba, o si rọ wọn lati tẹra mọ işẹ wọn ki awọn ma si şe tẹ ofin ẹgbẹ na loju. O rọ wọn pẹlu lati maa fọwọsọwọpọ.

Ọgbẹni G.A. Ibikunle ti işe Igbakeji Akọwe fun Ẹgbẹ A'agbafọ Iwọ-Oorun şalaye ofin ati ilana ẹgbẹ na fun wọn, o si rọ wọn lati tẹle ofin na.

Awọn oloye ẹgbẹ na ti o nipa ninu eto na ti nwọn si ba awọn enia na sọrọ, ti nwọn si wa lati olu ile işẹ ẹgbẹ na ni Ibadan ni: T. Oriọla, D. Şotuyọ Iyaafin Tọlani, Iyaafin Aşiyawu, D.D. Ekisanyan, ati G.O. Akinşọla

Ọgbẹni Bamidele Işọla, Ọgbẹni Lasisi Adebiyi ati Raimi Eyinogan wa nibẹ pẹlu, Ọgbẹni Bakare ti işe Olori ni Abẹokuta si dupẹ lọwọ awọn oloye Ẹgbẹ lati Ibadan lori eto na ti o yọri si rere.

# Mehaaya şa iyawo Baale pa

(Lati oju ewe kini)

pe, o le ni ọdun kanabọ ti alagbafọ na ti ngbe ile oun, bẹẹni ko si fi ejo iyawo oun sun oun ri nigbakan.

Ọba ilu na Ọba Adebayọ Akanji ati Eesa rẹ Oloye Salami Oyebọde jẹri nile ẹjọ pẹlu. Ọba na sọ pe nitootọ ni ọkọ obinrin na fa ọdaran na wa si aafin oun pe o pa oun ni iyawo. Ọba na sọ pe ọdaran na jẹwọ bẹẹ fun oun ati Eesa oun pẹlu, O ni lẹhin na ni awon lọ si ilu Ikirun nibiti Ọlọpa ti tẹle awọn wa si Ilie ti nwọn si mu ọdaran na lọ.

Ninu ẹri tirẹ niwaju ile ẹjọ, Ọlọpa ti o gba ọrọ enu ọdaran na sile ti Ise Ọtẹlẹmuyẹ Ọgbẹni Famuditimi sọ pe, gbangba ni ọdaran na jẹwọ fun oun pe, nitootọ ni oun pa obinrin na nitoripe ajẹ ni, ati pe ko jẹ ki oun gbadun aiye oun.

Ọlọpa na sọ pe, ọdaran na fi kun un pe, l'oru ọjọ ti işẹlẹ na şẹlẹ, oun ko gbadun oorun oun nitori pe bi obinrin na ti di eru okuta le oun l'ori l'o tun nfi maalu le oun kiri l'oju ala.

O ni nigbati ile mọ ni ọjọ keji, oun ko le sọrọ rara, ki nwon too mu oun lọ si ọdọ onişegun Babakekere ti o fun oun ni oogun lo ki oun too le sọrọ.

Ọlọpa na sọ siwaju si i pe, ọdaran na fi kun pe, lẹhin eyi ni agbari oun ho, ti oun si nje iro-ra. O ni bi oun ti njẹrora yi ni obinrin Baale oun wa joko lenu ọna iyara oun ti o si nfi oun korin pe: "Ta l'o l'awa ni baba ? Kai, a ni baba; Babakekere ni baba, Kai, a ni baba."

O ni ọdaran na sọ pe, nih'n ni inu ti bi oun, ti oun ki aake ọkọ obinrin na mọle, ti oun si le e de oju ọna oko nibiti oun şa a pa si.

Şugbọn ninu idajọ rẹ nile ẹjọ giga Oşogbo, Adajọ Ọlọla Christian Abimbọla sọ pe, gẹgẹbi ẹri ti o wa niwaju ile ejọ, oun da ọdaran na Tiamiyu Adigun lẹbi iku.

Adajọ na sọ pe, şugbọn ile ẹjọ gba pe ori ọdaran na ko pe ni akoko ti o daran na. Nitorina, o fi eto ẹjọ na ati idajọ l'ori rẹ şọwọ si Gomina lati sọ ifẹ ọkan rẹ l'ori idajọ na nitoripe bi o tilẹ jẹ pe ọkunrin yi jẹbi si iku, ori rẹ ko pe lakoko ti o huwa na.

| | | |
|---|---|---|
| 11 | 17 | 22 |
| | 6 | |
| | 9 | |
| | 10 | |

PRINTED AND PUBLISHED BY THE PEOPLES STAR PRESS N4/498B YEMETU ... P M B 5339 IBADAN ... (EDITOR) ...